Ẹni ti o ba mọọmọ parọ mọ mi, ki o yaa lọ wa ibùjókòó rẹ ninu ina

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Òjíṣẹ́ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: "Ẹni ti o ba mọọmọ parọ mọ mi, ki o yaa lọ wa ibùjókòó rẹ ninu ina".
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé pe dajudaju ẹni ti o ba mọọmọ parọ mọ ọn, pẹlu fifi ọrọ kan tabi iṣẹ kan ti si ọdọ rẹ ni ti irọ, dajudaju ibujokoo kan n bẹ fun un ni ọrun ninu ina; ki o maa jẹ ẹsan fun un lori pipa irọ mọ ọn.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/65043